# Ìdojúkọ iṣẹ ìdàgbàsókè saa ọdun Miliniọmu Ìjábọ Ọdún 2005.

United Nations



# Ìdojúkọ iṣẹ ìdàgbàsókè saa ọdun Miliniọmu Ìjábọ̀ Ọdun 2005

A Translation of "The Millennium Development Goals Report 2005" Into Yoruba

United Nations

NEW YORK, 2005

# Itesiwaju

Ifẹnuko lori idojukọ iṣẹ idagbasoke saa ọdun Miliniọmu ninu agbejade Ajọ Isọkan Orilẹ-ede Agbaye jẹ koko ijoko ipade kan ninu itan Ajọ Isọkan Orilẹ-ede Agbaye. O kun fun awọn ileri to buyari lati ọdọ awọn olori lagbaye ti wọn n jumọ ṣiṣẹ lorii wiwa alaafia, aabo, idagbasoke, ẹtọ ọmọ ẹda ati ominira fun gbogbo-gboo. Bi mo ti ṣe sọ ninu atẹjade mi kan ninu oṣu kẹta ọdun 2005 eyi ti akọle rẹ da lorii "Ninu oore ọfẹ ominira: itẹsiwaju ninu idagbasoke, aabo ati ẹtọ ọmọ-ẹda fun gbogbo-gboo" eyi ti ijabọ yii fi n tẹ siwaju: A kò lè gbadun idagbasoke laisi aabo, a kò lè gbadun aabo laisi idagbasoke bẹeni a kò lè gbadun ikankan ninu mejeeji laisi ibọwọ fun ẹtọ ọmọ-ẹda. Ayafi ti a ba gbaruku ti awọn igbésẹ wọnyi, kò ni si aṣeyọri lori ikankan wọn".

Adojukọ mejẹẹjọ ilana idagbasoke saa ọdun Miliniọmu bẹrẹ lati adinku si idaji ipo akuṣẹ lawujọ dori idena itàn kalẹ arun eedi (HIV/AIDS) ati pipésè eto ẹkọ ile-iwe alakọbẹrẹ fun gbogbo-gboo ki gbogbo rẹ ṣeeṣe ninu ọdun 2015. Gbogbo awọn nnkan wọnyi ni wọn jẹ koko adehun ti awọn orilẹ-ede kaakiri agbaye jumọ fọwọsi pẹlu awọn isọri ibiṣẹ idagbasoke lagbaye. Awọn ilana ti o rọrun ti o si tun lagbara ninu igbesẹ ti gbogbo ọkunrin ati obinrin ni awọn opopona, bẹrẹ lati ilu New York de Nairobi titi de New Delhi lè fara mọ pẹlu irọrun ati agbọye. Lati igba ti wọn tọ fọwọ sii, awọn ohun adojukọ yii ti kun fun akitiyan lati ṣe atilẹhin fun wiwa ojutu si iṣoro titosi ati airina airilò lagbaye.

Ki lo jẹ ki idojukọ idagbasoke saa ọdun Miliniomu yatọ? Idi mẹrin ló wà fun-un.

Lọna kini, idojukọ eto idagbasoke saa ọdun Miliniọmu da lori awọn eniyan, pẹlu dida asiko ati àgbéyẹwo aṣeyọri iṣẹ.

Lona keji, won da lori ifowo-sowopo ajumose lagbaye pelu atenu-mo ojuse awon orile-ede to sese n dide pe ki won tun ile won se ki awon orile-ede agba si gbaruku ti won ninu akitiyan wọn.

Lona keta, wọn tun ni atilehin to gira ninu ilana iseto ilu lati odo awon orile-ede to ti goke agba ati awọn to sese n dide, awon amuludun pẹlu awon ibise nlanla eleto iṣe idagbasoke.

Lọna kẹrin, awọn iṣẹ to ni aṣeyọri ni.

Ọdun 2005 ṣe Pataki pupọ fun wa lati dojukọ awọn iṣẹ naa laṣe yege. Ninu oṣu kẹsan ọdun karun lẹhin ti wọn fọwọ si awọn adojukọ yii, ti o si jẹ ọdun mẹwa si igba ti yó pari, gbogbo awọn olori lagbaye maa pade ni ilu New York tii ṣe olu ile-iṣẹ Ajọ Isọkan Orilẹ-ede Agbaye lati ṣe agbeyẹwo lorii bi ijẹjẹ wọn ṣe tẹwọn si, ki wọn si pinnu lori awọn igbésè miran to yẹ. Ni gbogbo ọna iṣẹ ti wọn doju kọ lọdun yi maa gbona giri-giri ju ti ọdun 2000 lọ. Dipo ki wọn maa ṣe agbekalẹ ilana adojukọ, lasiko yi awọn asiwaju gbọdọ pinnu lori ọna aseyọri iṣẹ.

ÌJÁBỌ̀ ITẸSIWAJU NINU IṢẸ: jẹ isiro jijabọ to kun rẹre ju, titi doni lorii ibi ti a ti n ba iṣẹ bọ ati ibi ti a n lọ ni ẹkun kọọkan kaakiri agbaye. O fiyeni lẹkun-rẹrẹ gbogbo akitiyan laarin awọn orisi-risi ẹka aṣoju ati awon ẹgbe ninu ati nita ibisẹ Ajọṣe Isọkan Agbaye. Gbogbo wọn pata ni wọn pese akọsilẹ isirò iṣẹ won ninu ojuṣe ẹka wọn, eyi ti o jẹki o rọrun lati gbe akosile ijabọ to pe pere-pere jade.

Ju gbogbo rẹ̀ lọ, akọsilẹ ijabọ yi fi hàn wa lori ilọsiwaju to waye ni awon agbegbe kan, pẹlu iru akitiyan ti a gbọdọ dawọle lati ṣe aṣeyọri idojukọ idagbasoke saa Miliniọmu ni awọn agbegbe miran. Bi a ti se n baa lọ yi, ewu n bẹ loko longẹ, nitori pe ọpọ lara awọn orilẹ-ede akuṣẹ ni won kò ni le jagun molu. Bi a ba si foju inu wo ibiti a ti n ba iṣẹ naa bọ, iru kikuna yi maa jẹ ipadanu anfaani tabua-tabua. Akọsilẹ ijabọ yi fi yeni pe o rọrun fun wa lati rii daju pe gbogbo awọn orilẹ-ede ni yo fẹrẹ mu ileri wọn ṣẹ lori awọn ohun ti a n lepa. Ojuṣe wa ni lati wa mu ileri naa ṣẹ

Bi mo ti se sọ ninu akọsilẹ ijabo mi ninu oṣu keta "E jẹki a sọrọ lorii ewu to le suyọ nipa pipadanu anfaani yi. Ọkẹ aimọye ẹmi to yẹ ki a gba la, ni a o

padanu; ọ̀pọ̀ ominira to yẹ ko waye ni a o sọnu bẹẹni a o maa gbe ninu aye ṣìlá-sìgbo ti kò ni ifọkanbalẹ.

Mo gbe ijabọ mi yii kalẹ gẹgẹ bi kọkọrọ ti yó si ipade ijiroro to n bọ ninu oṣu kẹsan, ti yo jẹ asiko ipinnu. Ìlàkàkà awọn ohun itọka si ati ẹkunrẹrẹ irohin ti o wà ninu rẹ, le jẹ iranlọwọ fun ẹnikọọkan, awọn ẹgbẹ ọmọluwabi, awọn ijọba, awọn ile igbimọ asofin ati awọn eniyan ọlọkan-o-jọkan lagbaye lati ṣe ojuṣe won fun aṣeyege awọn ohun idojukọ fun saa ọdun Miliniomu.

**KOFI A. ANNAN**
Akọwe Agba.

# Idojuko Ikini

1

## Gbigbogun ti ipo akuse ati ebi

Ọgọọrọ awọn eniyan lo wa ninu ipo akuṣẹ ti airina, airijẹ n ba wọn yipo lojoojumọ pẹlu owóna ti kò to dọla kan lojumọ. Ebi ati airi onjẹ ti o lokun jẹ tubọ n gberu sii. O lé ni ẹgbẹrun mẹrin-din-logun ọkẹ eniyan tii ebi n pa, ti wọn kò ri onjẹ jẹ lati fun wọn lokun. Airi onjẹ jẹ lewu pupọ fun awọn ọmọde, nitoripe o lè sọ wọn di alaabọ ara tabi ki wọn ma lè dàgbà bi o ti yẹ, kodà o le jẹki ọpọlọ wọn ku tabi pa wọn paapaa. O lé ni idá mẹrin awọn ọmọde ti ọjọ ori wọn kò ti i to ọdun marun ni awọn orilẹ-ede tó sẹsẹ̀ n dide ti wọn kò ri onjẹ amara lokun jẹ.

Jijagun molu lori ipo akuṣẹ ati ebi jẹ ohun ti o rọrun lati ṣe. Ni iha ilẹ Asia, bi idan ni wọn n din airina ati ipo akuṣẹ kù lawujọ wọn. Laarin ọdun 1990 si 2001 iye awọn ti owóna wọn lojumọ kò to dọla kan ti din kù bii ida mẹrin biliọnu kan --- asiko ti ọrọ-aje wọn buyaari ni yi. Laarin ọdun mẹwa sẹhin, awọn orilẹ-ede bii ọgbọn tabi ju bẹ lọ ni bii ida-mẹrin ti dinku ninu airijẹ ati ebi. Mẹrinla lara awọn orilẹ-ede yi ni wọn wà ni agbegbe aṣalẹ ilẹ Afirika nibiti ọwọ́n onjẹ ati ebi doju kọ.

# Idojuko Ikejì 2

## Aseyori ninu eto eko ile-iwe alakobere ti kariaye

Imọ ẹ̀kọ́ n fún awọn eniyan ni anfaani lati yan iru ìgbé aye ti wọn ba fẹ. O n fun wọn ni igboya lati lè sọ èrò ọkan wọn laarin ẹgbẹ, lawujọ ati nibi iṣẹ. Ṣugbọn, o lé ni ọọdunrun-le-lẹgbẹta ọ̀kẹ́, awọn ọmọ ti wọn ti to wọ ile-ẹkọ alakọbẹrẹ ti wọn padanu iru ẹ̀tọ́ ọmọ-eda yi . Ọpọ awọn ọmọ wọ̀nyi ni wọn jẹyọ lati idile akuṣẹ, ti ìyà wọn kò tilẹ ni imọ ẹ̀kọ́ rara.

Awọn ọmọde nikan kọ ni kò ni iru anfaani yii. Imọ ẹkọ, paapaa fun awọn obinrin kún fun ọ̀pọ̀ anfaani ohun afẹ ati ọrọ-aje lawujọ. Awọn ọ̀mọ̀wé obinrin ni anfaani iṣẹ ọrọ-aje ti wọn si n riṣẹ ṣe laarin ilu lẹnu iṣẹ ijọba. Gẹgẹ bi iya, wọn maa n bimọ diẹ ti wọn lokun ti wọn sì le ni irèti lati lọ sile-iwe. Gbogbo iru anfaani wọnyi lo n pana ipò akúṣẹ̀ lawujọ.

Ẹkùn márùn lo sunmọ igbani-wọle ẹkọ alakọbẹrẹ kari-aye. Ki iru aṣeyori bayi tó lè waye awọn ẹkun iha kan ni Afirika, iha guusu ilẹ Asia ati awọn ẹkun eti bèbè okun gbọdọ tẹra mọ iyanju gidi lai boju wẹ̀hìn.

Ni kaakiri awọn ẹkun wọnyi ati awọn ibomiran ti wọn ba fẹ gba awọn ọmọ wọle fun imọ ẹko alakọbẹrẹ lati gbòòrò si i, wọn gbọ́dọ̀ fi taratara gbiyanju lati rii daju pe gbogbo awọn ọmọde, paapaa julọ awọn ti kò rọrùn lati tètè ri ni anfaani lati wà nile-ẹkọ fun imọ ẹkọ to yè kooro.

# Idojuko Iketa 3

## Agbe-laruge eto ni dogba-n-dogba fun tako-tabo ati wiwa ibudo agbara fun awon obinrin.

Ètọ́ fun takọ-tabo ni dọgba-n-dọgba jẹ ẹ̀tọ́ ọmọ-ẹda ti o si jẹ ẹ̀mí fún aṣeyọri awọn ohun adojukọ fun saa ọdun Miliniọmu. Dandan ni lati ṣẹgun ebi, titálákà ati aisan. Eyi jasi didọgba ninu gbogbo ipo imọ ẹkọ ati ni awọn ẹka gbogbo iṣẹ, idọgba ninu ẹ̀tọ́ lori ohun alumọni tabi iṣura pẹlu didọgba lorii yiyan awọn aṣoju lawujọ ati sinu ipo ọ̀ṣẹ̀lú.

Ayọrisi idọgba ninu ẹ̀tọ̀ ẹko ni ile-iwe alakọbẹrẹ ati giga ṣe pataki pupọ bi awọn obinrin ba maa riṣẹ se lawujọ ati ninu eto iṣẹ ọrọ-aje lagbaye. Ṣugbọn ni ọpọlọpọ orilẹ-ede ni wọn ti yọ awọn obinrin sẹ́hìn. Lara ọ̀pọ̀ anfaani tó sujọ ninu imọ ẹkọ gidi lati ri ifọkanbalẹ iṣẹ olowó oṣu. Ṣugbọn nigba miran ifọwọ rọ awọn obinrin sẹ́hìn sinu iṣẹ ti kò lowó lori maa n waye. Bi o tilẹ jẹ pe awọn obinrin ti fi kun akitiyan wọn ninu iṣẹ olowó oṣu yatọ si iṣẹ ọgbin, ṣibẹ-ṣibẹ wọn kere púpọ̀ ninu iṣẹ olowó oṣu ni ọpọ orilẹ-ede, ti wọn si pọ nibi iṣẹ aláfọwọ ṣe.

Ẹ̀tọ́ dọgba-n-dọgba lati lẹnu ninu ipinnu ọrọ ti ó kan igbési ayé wọn lati inu ẹbi de ẹka iṣakoso ijọba jẹ kọkọrọ itú idè okùn agbara awọn obinrin. Bi o tilẹ jẹ wi pe iye awọn obinrin to n ṣoju ni ile igbimọ apapọ ti n pọ sii lati ọdun 1990, sibẹ naa awọn obinrin kò ti i ju ida mẹrin-din-logun ninu ọgọrun lọ ninu ipo aṣoju ni kaakiri àgbaye.

# Idojuko Ikerin

4

# Adinku lorii Iku ogo weere

Ijamba nla gbaa ni iku ọmọde, sibẹ o fẹrẹ to oji-le-lugba ọkẹ awọn ọmọ tó n ku lọdọọdun iyẹn ja si ẹgbẹrun lọna ọgbọn lo n ku lojojumọ ki wọn to pe ọmọ ọdun marun. Ọpọ lara awọn ọmọ wọnyi ni wọn n gbe lorilẹ-ede to sẹ̀sẹ̀ n dide ti wọn n ku iku arùn tabi awọ́pọ̀ arun to yẹ ki a kapa tabi awọn eyi ti a lè kapa, tabi awọn eyi ti a lè wòsàn pẹlu inawo diẹ. Nigba miran isẹlẹ iku yi lè jẹ lori aisi egboogi ti kò gbowó lori lati fi wo arun òtútù àyà tabi lilo omi gbigbona-wọọrọ pẹlu iyọ lati fi di igbẹ gbuuru duro fun awọn ọmọde. Airi onjẹ to lokun jẹ lo n fa idaji ninu iku wọnyi,

Ò̀sì ati ìṣẹ́ lo n fa iku awọn ọdọmọde: Aisi itọju to peye fun awọn ogo-wẹẹrẹ ati awọn ọdọ-mọde wọọ laarin awọn eniyan lawọn orilẹ-ede akúṣẹ̀ ati awọn akuṣẹ tó wà lawọn orilẹ-ede gbajumọ. Ilọsiwaju ninu ètò iṣẹ ilera jẹ ohun Pataki pẹlu omi to dara ati eto ayika to bojumu. Imọ-ẹkọ fun awọn obinrin ati fun awọn iya jẹ ọna kan lati gba ẹmi awọn ọmọde la. Afikun owónà tabi owó oṣu lè jẹ iranlọwọ, ṣugbọn diẹ ni aṣeyọri tó lè suyọ ayafi ti a ba jẹki eto iṣẹ yi de ọdọ awọn tọrọ yi kan gbọ̀n-gbọ̀n.

# Idojuko Ikarun 5

# Isodotun Ilera Alaboyun

Ọmọ bibi gbodọ jẹ ohun ayọ. Ṣugbọn fun awọn obinrin bii ilaji ọkẹ kan lọdọọdun ni liloyun ati irobi wọn maa n jasi iku. Iye iru eyi lona ogun awọn obinrin lo n jẹ rora tabi fara gbọgbẹ, ti o jasi pe ti wọn kò ba tete ri itọju, o le da ailera pẹlu jijẹ oró nigbesi aye wọn silẹ. Iku abiyamọ maa jẹ ọgbun ifoya ati ipayin-keke fun awọn ọmọ ti wọn ba bi.

Awọn orilẹ-ede ti iṣẹlẹ iku aboyun ti n dinku ti ni itẹsiwaju ṣugbọn eleyi kò to. Bi awọn orilẹ-ede ti wọn wà ninu ọ̀gbun iṣẹlẹ yii ba fẹ iyọra, wọn gbọ́dọ̀ ni afikun owóna lati ri i daju pe wọn gba awọn dokita, nọọsi ati awọn olugbebi fun abojuto iṣẹ yi. Bi iṣoro ọmọ-bibi ba fẹ suyọ, awọn abiyamọ gbọdọ ni anfaani si ile-iwosan to peye.

Ile-itọju alabiyamọ gbọdọ wà ni arọwọ to gbogbo-gbòò, pẹlu ifètò somọ-bibi, eyi to kọkọ yẹ ninu ètò ọmọ-bibi. O ṣe pataki pupọ lati bojuto ọkẹ aimọye awọn ọ̀dọ́ ti wọn kò ni pẹ bẹ̀rẹ̀ si sòwò ọmọ bibi. Ni bayi ẹgbẹrun merin ọkẹ ni iye obinrin ti wọn kò ri itọju to yẹ fun aabo ati gbigba egboogi to yẹ fun oyun.

# Idojuko Ikefa 6

## Igbogun ti arun eedi (HIV/AIDS) iba ati awon arun miran.

Lati odun keẹdogbọn ti arun eedi ti jeyọ ni arun yi ti di ogbontagiri aṣeku pani logbodò ni iha Gunsu Afirika, kódà ipo kerin ló wà lara awọn arun aseku pani lagbaye. O ti lé ni irinwo ọkẹ eniyan ti arun yi ti ṣeku pa ni kaakiri agbaye, lati igbà ti o ti seyọ. Bẹẹni nipari odun 2004, o to ẹẹdẹgbẹrin ọkẹ eniyan ti kokoro arun yi n ba jà. Yatọ si ọgọọrọ awọn ọmọ-ẹda ti arun eedi ti ba aye wọn je. Arun yi ti pana ilọsiwaju ni kaakiri awọn orilẹ-ede to ti jẹyọ. Ko si orile-ede ti arun yi ko ba wẹkẹ. Ṣugbọn awọn orilẹ-ede kan ti gbogun ti i, wọn si n sẹgun. Awọn orilẹ-ede Thailand ati Uganda ti fi hàn pe pẹlu idojukọ ati iwa akinkanju kiko arun yi le dínkù. Apẹẹrẹ rere ni wọn jẹ fun awọn orile-ede miran ti wọn wa ninu ọgbun arun eedi.

Bi o ti lẹ je wi pe awọn arun miran ko tii gbajumọ, sibẹ-sibẹ wọn ń ko irẹwẹsi ba awọn eniyan orilẹ-ede to sèsè n dide lagbaye. Arun iba n pa ogun ọkẹ eniyan lọdun kan, ti awọn ọmọde si pọ ninu wọn. Bẹẹni kò jẹki eto iṣẹ ọrọ-aje awọn orilẹ-ede Afirika gbooro siwaju. Arun ikọ ẹgbẹ taa n lero pe o ti kásẹ n lẹ, ti tun gberi yọ, pẹlu atilẹhin arun kò gboogun eedi. Ko ni jẹ ohun iyanu lati rii pe awọn arun mẹtẹta wọnyi ti fi awọn orilẹ-ede akuṣẹ ṣe ile. Ṣugbọn a le dènà wọn nipa igbélarugẹ eto ẹkọ, ṣiṣe eto idena pẹlu yiyara gba itoju to yẹ bi awọn arun naa ba ti suyọ.

# Idojuko Ikeje

7

# Imudani-loju eto ayika to peye

Ayika to bojumu jẹ agbekalẹ ta a fi awọn ohun alumọni ṣe fun atọkun alaafia. Ṣugbọn lilepa ilana yi kò ni bọsi lorii bi a ṣe n lo awọn nnkan alumọni yi. Ilẹ ti n sa, beẹni awọn ohun èrè oko ati awọn ẹranko lorişi-risi ti nkasẹ nlẹ. Oju ọjọ ti nyipo, kò si duro loju kan, bẹẹ ni o n mu omi etikun ya wọlu ti atẹgun oorun n buru sii pẹlu agbara òjò. Gbogbo òdò ati òkun ni a ti fẹrẹ pẹja tan. Awọn akuṣẹ ni igberiko ni ọrọ naa kàn ju, nitori pe igbẹkẹle wọn fun onjẹ oojo ati igbé aye wọn da lori awọn ohun alumọni ayika wọn. Bi o tilẹ jẹ pe ọgọọrọ awọn eniyan ni wọn ya kúrò ni igberiko lọ si ilu nlanla, sibẹsibẹ afikun ni o jẹ fun awọn ilu wọnyi ti kò si aabo ṣugbọn ti o kun fun awọ́pọ̀ eniyan.

Ni awọn agbegbe ilu nla ati igberiko ọgọọrọ eniyan ni wọn kò ri omi to dara lati mu ati ayika to bojumu. Ifọwọ́-sowọpọ gidi lagbaye gbọdọ jẹyọ lati koju awọn iṣẹlẹ wọnyi pẹlu iṣoro ayika ti awọn akuṣẹ n ba wẹkẹ. Akitiyan lorii àdàlú-dápọ̀ inu afẹfẹ fi hàn gbangba pe ilọsiwaju ati aṣeyọri le waye bi ẹmi isèlú ba wà.

# Idojuko Ikejo

8

## Titepele mo ajosepo lagbaye fun idagbasoke

Gbongbo ilana èto idagbasoke awọn ohun adojukọ ni saa Miliniomu je ifimo-sọkan lati gbogun ti airina airilo eyi ti gbogbo orilẹ-ede gbọdọ fohun sọkan lati jagun molu. Ojuṣe lati jagun molu wà lọwo awọn orile-ede to sèsè n dide. Ṣugbọn sa, atilẹhin agbaye ṣe Pataki paapaa julọ fun awon akusẹ orile-ede ati awọn orilẹ-ede ti ibugbe wọn dafo. Siwaju sii lori isowopọ ọro-aje agbaye, isowọ-pọ lai si idiwọ, ifọkan-balẹ eto inawo lagbaye pelu itànkalè imọ ilo ẹrọ ode-oni jẹ atọkun fun awọn orilẹ-ede to sese n dide lati ni anfaani kiakia ati ifesẹ rinlẹ idagbasoke.

Idojukọ Ajọ Isọkn Orile-ede Agbaye ni saa Miliniọmu yi, jẹ ajọmò adehun pe awọn orilẹ-ede to sẹsẹ n dide gbodọ sakitiyan lati ni èto ọrọ-aje to duro deede fun aridaju idagbasoke wọn. Ki wọn si le bojuto awọn ohun eto omo ẹda. Ni ti awọn orilẹ-ede àgbà wọn gba lati ṣe atilẹhin fun awọn akuse orilẹ-ede nipa eto iṣòwò, iranlọwọ owó ati itukun gbèsè fun wọn. Ajumose to nj itumọ gbọdọ waye laarin olowó ati talaka pẹlu titọ-pinpin awon ohun to n je awọn orilẹ-ede tó sèsè n dide logun bii imo ilò ẹro, imo eko isegun ati pipesi ise fun ọgọọrọ awọn eniyan wọn. Paapaa fun ọpọ awọn odo ati agunbaniro.

Asìkò ode òní, jẹ iran kini to ni ohun iṣura ati imọ ilò ẹrọ lati mu ẹ̀tọ́ ètò ìdàgbàsókè bá ẹnikọọkan ati lati yọ iran ọmọ-ẹda kuro ninu airina, airilo. Erongba lori idagbasoke jẹ ti gbogbo wa. Idojukọ ìdàgbàsókè saa Miliniọmu eyi ti o bẹrẹ lati orii ipo akuṣẹ titi dorii fifi awọn ogo wẹẹrẹ si ile-ẹkọ alakọbẹrẹ ati igbogun ti itànkálẹ̀ arun eedi (HIV/AIDS) ki o to di odun 2015, ti di eto kariaye ati ategun ilọsiwaju eyi ti gbogbo awọn alaanu, olùrànlọwọ̀ owó, awọn orilẹ-ede tó sẹ̀sẹ̀ n dide, ẹgbẹ amuludun ati awọn ile-iṣẹ ètò ìdàgbàsókè ọlọkan-o-jọkan gbaruku ti i tara-tara.

Awọn ohun idojukọ wọnyi gbọdọ seese ninu ọdun 2015 ṣugbọn ayafi ti gbogbo awọn tọ́rọ̀ naa kan ba jumọ dòwòpọ̀ bi ti atẹ̀hin wa ki wọ́n si yara bi ọgan bẹrẹ akitiyan wọn.

Published by **United Nations Information Centre** Lagos.
Tel: 01-2694886
Printed by **donald rowlands** LTD 08023007520